**Press Release**

# *ASHÁWÓ: Ta ló sọ wípé alágbèrè ni ẹ́??*

## apexart - Lagos, Nigeria



Elfrida Grey, *Ìrètí Nínú Rògbòdiyàn*, 2024

Olutọju aworan **Amaechina David SNIPES**

Awọn ọjọ:
**June 29th - July 27th 2024, 10am - 7pm**

Gbigbawọle ṣiṣi: **June 29th, 2024. 12pm - 7pm**

Ibi: **Oworoshoki Youth Sport Centre (Papa)**
**Prince kb Oloworo street, Lagos, Nigeria**

Awọn oṣere:
**Janet Adenike Adebayo - Blessing Offiong Ekpenyong - Elfrida Grey - Oluwabukunmi Olukitibi**

*"Gba ìgbéga láti ibi iṣẹ́ - Asháwó*
*Lọ fún ìnasẹ̀ ìgbáfẹ́ ni alẹ́, láì mú ẹlòmíràn lọ́wọ́ - Asháwó*
*Jẹ́ ìyá ń dágbé, tí ń ṣe olùdátọ́ ọmọ - Asháwó*
*Ra ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ - Asháwó*
*Wí fún ọlọ́jà nínú ọjà kí ó ma ṣe fi ọwọ́ kàn ọ́ - Asháwó*
*Fakọyọ nínú ẹ̀kọ́ ìwé rẹ - Asháwó*
*Èmi! Asháwó! Ìwọ, Asháwó! Gbogbo wa, Asháwó!"*

Àkọlé ìfihàn yìí "Asháwó", jẹ́ ọ̀rọ̀ ìkélé tí à ń lò ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà láti tọ́ka sí òṣìṣẹ́ ìbálòpọ̀ tàbí ọlọ́jà alẹ́.

Pẹ̀lú ìmúṣinṣin ètò ìṣèlú tí ó fàyè gba àwọn ọkùnrin láti gàba lé obìnrin lórí ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, ọ̀rọ̀ ìkélé náà ti bú ramúramù láti ọ̀rọ̀ àlùfànsá di àmì ẹ̀tanú fún gbogbo obìnrin ilẹ̀ Nàìjíríà. Obìnrin orílẹ̀ èdè Nàìjíríà, ní ìfàyègbà kékeré rẹ̀ mọ̀ dájú ṣáká pé òun le kan àbùkù ọ̀rọ̀ náà, níbikíbi àti lójojúmọ́ pẹ̀lú.

Ìfihàn àpapọ̀ yìí ní ṣe pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ láti ọwọ́ àwọn olúda l'óbìnrin láti ìlú Èkó, ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Nípa ìlànà ìṣe bí oge ṣíṣe, àkọsílẹ̀ amóhùnmáwòrán àti onírúurú iṣẹ́ ọnà àfojurí òun ìtàgé, àwọn obìnrin yìí fọhùn lórí ẹ̀gbín nìì tí ń kojú àwọn obìnrin orílẹ̀ èdè Nàìjíríà : ipa ìfaradà wọn, ìdáhùn àti ìfojúsùn gbogbogbò lórí ìṣẹ̀lẹ̀ náà láti sọ ọ́ di mímọ̀ jinlẹ̀jinlẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni gbígbé gègé lé àwọn ọ̀nà àbáyọ tí ó le pa ọ̀rọ̀ ẹ̀tanú yìí run bámubámu.

Àyípadà ìtàn náà kò le wáyé láti ọ̀dọ̀ àwọn olùfaragbá nìkan. Àfihàn yìí ń gbèrò láti pe àwọn ọkùnrin Nàìjíríà níjà, nítorí àwọn gan-an ni ọ̀dádá gbòógí nínú ọ̀ràn yìí, kí wọ́n lè fọwó sowọ́pọ̀ fún ìdánilójú ìgbárùkùtì àti ìkópa nínú ṣíṣẹ̀ dá àyíká tí ó ní ààbò, tí ó rọ'ni lọ́rùn, tí ó sì ní ìyọ̀nda fún àwọn obìnrin orílẹ̀ èdè Nàìjíríà láti gbèrú.

*[ASHÁWÓ: Ta ló sọ wípé alágbèrè ni ẹ́??] jẹ́ àṣàyàn nínú ìpè gbogbogbo ikọ̀ Apexart. Fún àlàyé ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àti àwòrán, o lè kàn sí https://apexart.org/snipes.php. tàbí kí o fi ọ̀rọ̀ ṣọwọ́ sí ash.hagerstrand@apexart.org*

---

**David Amaechina**, tí ìnagijẹ rẹ̀ ń jẹ́ **SNIPES** ń ṣe olùdá eré oníṣe òun aláré ìtàgé ọlọ́nà púpọ̀, oníjó sẹ́lẹ́nsẹ́ oní-tẹ̀lé-ǹ-tẹ̀lé pẹ̀lú pẹ̀lú olùṣètò agbègbè, tí ó sì fi ìlú Èkó, ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà ṣe ibùgbé. Iṣẹ́ rẹ wulẹ̀ máa ń dá lórí ìmúdàgbà àsìkò sí àsìkò ní ìfojúsùn adúláwọ̀ (Áfíríkà); bákan náà ló sì tún ya kan àwọn ìṣe ìtàgé tí ń jẹyọ láti inú kùsà ìrántí, àlọ́ àsìkò àti àwọn àṣà, ìṣe àmúfikún àgbáyé tí òún ní ìrírí gbòògì pẹ̀lú.

**apexart**'s program supporters past and present include the Milton and Sally Avery Arts Foundation, the Kettering Family Foundation, the National Endowment for the Arts, the Buhl Foundation,Bloomberg Philanthropies, Spencer Brownstone, the Kenneth A. Cowin Foundation, Epstein Teicher Philanthropies, The Greenwich Collection Ltd., William Talbott Hillman Foundation/Affirmation Arts Fund, the Fifth Floor Foundation, The Puffin Foundation, the Trust for Mutual Understanding, The Andy Warhol Foundation for the Visual Arts, and public funds from the New York City Department of Cultural Affairs in partnership with the City Council, public funds from Creative Engagement, supported by the New York State Council on the Arts with the support of Governor Andrew Cuomo and administered by LMCC, funds from NYSCA Electronic Media/Film in Partnership with Wave Farm: Media Arts Assistance Fund, with the support of Governor Andrew Cuomo and the New York State Legislature, as well as the New York State Council on the Arts with the support of the New York State Legislature.

**#ASHAWO**

**291 church street, new york, ny 10013**
**t +1 212 431 5270 www.apexart.org**